# Alaye ni Ede Geesi fun
# awon obi ati abanitoju omo

WORKaBOOK®

**Kini awon Iwe Ikose Agberele (Workabooks)?**
Awon Iwe Akose Agberele ni ohun gbogbo ti omo re nilo ni ile iwe, ninu ise kan, fun odun kan ni ile iwe.

Ise ninu Iwe Ikose Agberele je ise ti o romo ise kilasi ti a si se ko le romo Korikulomu Orile Ede. Ise ninu Iwe Ikose Agberele je ise ti o yapa si ona meta ototo: Ikowe, Isise Lemolemo, Rironu.

**Awon akitiyan ikowe**
Eleyi je awon ohun ti omo re ni lati ko ni odun yi. Awon kan, biii awon tabili isiro ati igbeyewo oro, je awon ohun ti a ni lati fi okan ko. Awon iwe yi wa ni kikun ni alawo bulu fun (isiro) ati alawo osan fun (Ede Geesi).

Fun awon akitiyan ikowe, itunse je pataki ati wipe o sese ki o fe danrawo oye bii awon tabili isiro nigba ti o ba nlo ati ti o nbo lati ile iwe.

**Awon akitiyan isise lemolemo**
A se igbekale awon akitiyan isise lemolemo lati ri wipe ikeko je aseyori. Wa ri won lori awon ewe ti a kun ni alawo orenji fun (isiro) tabi populu fun (Ede Geesi). Awon akitiyan wonyi wa loke meta ototo:

- Oke A: Lati ri wipe akeko se aseyori ti o ye fun kilasi re;
- Oke B: Lati ri wipe awon ti orile ede fi lele je ni sise;
- Oke C: Lati sagbekale awon ise ti won ma mu ki akeko tiraka daradara.

Ipese awom akitiyan wonyi yio je ki gbogbo awon omo lati saseyori ati tesiwaju. Oluko ni yio mu iru akitiyan ti o ye ki omo se, sugbon bi omo re ba fe mu akitiyan ti oke re ga ju eyi ti oluko mu fun, gba omo re niyanju pe ki o mu akitiyan ti o ga ju yi si!

**Awon akitiyan rironu**
Awon Akitiyan Rironu (ati Kikowe) fihan awon ona ti a le lo isiro ati Ede Geesi ni igbe aye ojojumo. A kun awon yi ni alawo ewe fun (isiro) ati pupa fun (Ede Geesi). Won mulo awon odan ti akeko ko nipa sise awon akitiyan ikowe ati isise lemolemo.

Awon Iwe Ikose Agberele tun ni awon ohun wonyi:

- ***Iwe pelebe itumo ede (mini dictionary)*** ti o ni awon oro pataki fun odun. Awon omo le lo iwe yi lati ko itumo ede fun rara won ninu odun;
- ***Awon ewe alawo gire*** fun ikowe kukuru tabi awon ise ti o tayo miran;
- ***Ewe aseyori*** fokun fun awon omo lati pari Iwe Ikose Agberele;
- fun Ede Geesi, ***ewe rekodu iwe kika*** nje ki a ni oyaya fun ikawe;
- fun isiro, ***atoka*** ni alaye ni kikun ati awon iwe alaye omiran ti won se iranwo fun kiko isiro.

**Bibere**
Ise Agberele yio wa ni osose. Ni kilasi, omo re yio ko sile sinu Iwe Ikose Agberele re awon akitiyan ti a fun lati se. Nigba ti omo re ba bere si ni se ise agberele re, wo ise re kio le mo boya o mo ohun ti o ye kio se. O ye ki won gbiyanju lati se ise agberele won lai si iranlowo re, sugbon o le fun won ni iranlowo ati idamoran nigbakugba ti won ba nilo re.

Ri wipe won ni ohun ti won le gbara le ati pe ki won lo pensulu – lati le mu ki ipare isise ise rorun!

Pupo ninu awon akitiyan wonyi la le se ni asiko igba isise kan bi o te je pe die ninu awon Akitiyan Rironu le je ni sise fun ojo meji si meta, fun apere, kiko rekodu igba ti omo lo lati de ile iwe.

Fifun omo re ni ayika ti o ye fun sise ise agberele se pataki fun riran omo re lowo. Bi awon wonyi:

***Sise ise nigba ti o dara***
Sise ise nigba ti o dara se pataki nitori naa tiraka lati wa igba dede fun sise ise nigba ti ko re omo re pupopupo, fun apere, ni Ojo Abameta tabi Ojo Isimi. Igba yi ye ko je asiko ti o ma wa nibe ati ti o le fun omo re ni iranlowo bi o ba nilo re.

***Awon idaamu***
Tiraka lati wa ibi ti o dake fun omo re lati se ise agberele. Ibi yi lati je ibi ti o ni ina dara dara ati ti ko ni idoti. Gba awon ti won wa ni ile re niyanju wipe ki won ma da omo re lamu nigba ti o ba nse ise agberele re!

© PSHB Co Ltd Odun 2005, 2014

***Awon ohun ti omo re nilo***
Ri wipe ko re omo re ju, tabi ebi npa, ongbe ngbe, o tutu tabi ara re ko bale nigba ti o ba joko lati se ise agberele re. Awon nkan bayi yio se jamba fun fifojusi ati kikowe.

Nigba ti omo re ba pari, o ye ki o fowobuwe ise agberele re lati fihan pe o ti pari re. Fowobuwe sinu apoti oro fun awon obi/abanitoju omo, leyin eyi fagile ikan ninu awon apoti wonyi:

- ***Pelu iranlowo*** bi omo re ba nilo iranlowo;
- ***Fun rara re*** Bi omo re ba sise fun rara re;
- ***Pelu idaniloju*** Bi omo re ba sise fun rara re ati pelu idaniloju.

Aye wa pelu fun o lati koro sile fun oluko – lati salaye wahala kan, tabi aseyori ti o tayo, fun apere. Ni akojo, ri wipe iwe yi lo si ile iwe ni ojo ti o ye.

**Bi o se le se iranlowo – yin ati kio gba niyanju**
Gege bi obi/abanitoju omo, o ni agbara pupopupo lati fokun fun idaniloju omo re – ati wipe idaniloju se pataki fun ikeko.

Ohun kan ti o le se ni lati gba omo re niyanju lati se ise agberele ti a gbe fun ati leyin eyi ki o ran lowo nigba ti o ba nse e. Ko se pataki pe ki o mo gbogbo idahun si awon ibere – jije ki omo re mo pe okan re wa lori ohun ti o nse ni ohun ti o se pataki!

Bi omo re ko ba ni idaju nipa ise agberele re, ka awon akitiyan inu re pelu omo re ati ki o bere awon 'atokun' ibere, bi awon wonyi:

- ***Se o le se alaye ohun ti o nse fun mi?***
- ***Bawo ni o se ma se eleyi?***
- ***Bawo lo se mo ohun ti o ye ko se?***
- ***Kini o ni lati wa ri?***

Nigba ti o ba soro nipa ise agberele ni ona yi pelu omo re, omo re yio bo si ipo 'oluko' ati salaye ohun ti o ye ki o se. Igbese yi fun rara re le je pataki.

Ni gbogbo igba, fun omo re ni iranlowo, iyin, ati igbiyanju lanti lanti! Tiraka lati fun omo re ni iyin pato ti o je mo eya tabi ibi kan nipa ise re, nipa lilo awon oro bii awon wonyi: "Mo feran bi o se se…"; ati nigba gbogbo sagbateru omo re ki o ba le ni inu didun si ise re.

Ati bi asiko ba ti nlo, iranlowo ati agbateru fun ise agberele le wa latodo enikeni ti a ba fara le – o le je egbon okunrin, anti, obi obi, tabi eni to ngbe leba ile; ko pon dandan pe o ni lati je enikan naa nigba gbogbo.

**Ikeko ni lati je ohun ajumo se pelu ifowosowopo ile omo ati ile iwe ati ise agberele le je okunfa ti o so po awon ohun meji igbe aye omo re yi. Nipa fifowosowopo pelu ile iwe, o se agbateru ti o ga fun ikeko omo re!**

***Fun alaye ni kikun, lo si ori itakun agbaye wa: www.workabook.co.uk***

*Itumo ede ati igbewepo: worldaccent.com*

© PSHB Co Ltd Odun 2005, 2014 